# AJINDE IRETI ONIGBAGBỌ́

**1 Kọrinti 15:1-58**

**ẸKỌ 379 -- FUN AWỌN AGBA**

**AKỌSORI: "Bi a kò ba si ji Kristi dide, asan ni igbagbọ́ nyin; ẹnyin wà ninu ẹ̀ṣẹ nyin sibẹ" (1 Kọrinti 15:17).**

## I Otitọ ti Ajinde Kristi ninu Ara

1. Paulu ti waasu Ihinrere fun awọn ara Kọrinti, nipasẹ eyi ti wọn fi ri igbala, 1 Kọrinti 15:1, 2; Romu 1:16.
2. Gẹgẹ bi Iwe Mimọ́ ti wi, nipa iku ati Ajinde Kristi ni a ti le ri igbala, 1 Kọrinti 15:3; Isaiah 53:5; Jobu 19:25-27; Luku 24:46, 47.
3. Awọn Apọsteli ati awọn ọmọ ẹyin Jesu jẹ́ ẹlẹri ojukoju ajinde Rẹ̀, 1 Kọrinti 15:5-11; Luku 24:33-43; Iṣe Awọn Apọsteli 9:3-5

## II Awọn Miiran Sẹ́ Ajinde Kristi

1 Bi Kristi kò ba jinde, iwaasu Ihinrere ati igbagbọ́ ninu Rẹ̀ ja si asán, 1 Kọrinti 15:12-14; Romu 4:25.

2 Bi Kristi kò ba jinde, awọn Aposteli ati awọn ọmọ-lẹyin Jesu jẹ́ ẹlẹri eke, 1 Kọrinti 15:15; Iṣe Awọn Apọsteli 10:39-41.

3 Bi Kristi kò ba jinde, awọn Onigbagbọ́ wà ninu ẹ̀ṣẹ wọn sibẹ, awọn ti o si kú ninu Kristi ṣegbe, 1 Kọrinti 15:16-19;

1 Tẹssalonika 4:13, 14.

## III Idaniloju Ajinde Awọn Onigbagbọ́

1 Kristi di akọbi ninu awọn ti o sùn, 1 Kọrinti 15:20; Lefitiku 23:10, 11; Matthew 27:52, 53.

2 Lẹyin naa olukuluku eniyan ni ipa tirẹ̀, awọn ti iṣe ti Kristi ni bibọ̀ Rẹ̀, 1 Kọrinti 15:23; Filippi 3:10, 11; Ifihan 20:6.

3 Nigba ti o ṣe pe nipa eniyan ni ikú ti wá, nipa eniyan ni ajinde kuro ninu okú ti wá pẹlu, 1 Kọrinti 15:21, 22; Isaiah 26:19; Johannu 5:28, 29.

## IV Iṣẹgun Ikẹyin Kristi Lori Gbogbo Awọn Ọta Rẹ̀

1 Lẹyin ti Kristi ba sọ gbogbo ijọba ati aṣẹ kalẹ̀, ikú ni ọta ikẹyin ti a o parun, 1 Kọrinti 15:24-26; Orin Dafidi 2:8, 9; Ifihan 20:7-15.

2 Nigba ti a ba ti fi ohun gbogbo sabẹ ẹsẹ Rẹ̀, Kristi nikan ṣoṣo ni o kù, 1 Kọrinti 15:25; Filippi 2:5-11.

3 Nigba naa ni a o fi Ọmọ sabẹ ẹsẹ Baba, ki Ọlọrun ki O le jasi ohun gbogbo ninu ohun gbogbo, 1 Kọrinti 15:28; Johannu 14:28.

## V Ireti Onigbagbọ́ nipa igbesi-ayé ti N bọ̀

1 Iribọmi jẹ́ apẹẹrẹ ikú, isinku ati ajinde pẹlu Kristi, 1 Kọrinti 15:29; Romu 6:3, 4.

2 Paulu n kú lojoojumọ ki oun ki o ba le ṣe deedee pẹlu ikú Kristi, 1 Kọrinti 15:30-32; Filippi 3:10, 11; Romu 8:18.

3 Ireti ayé ti n bọ̀ a maa sọ ọkàn Onigbabọ ji si ododo,

1 Kọrinti 15:33, 34.

## VI Irú Ara ti Awọn ti o kú yoo Gbé Wọ̀ nigba Ajinde

1 Gẹgẹ bi a ti i gbin irugbin ti i si i dagba, bẹẹ gẹgẹ ni a fun olukuluku irugbin ni ara ti rẹ, 1 Kọrinti 15:35-38; Luku 24:39.

2 Gẹgẹ bi ogo ti ayé ti yatọ si ogo ti oke Ọrun, bakan naa ni ara-iyara yatọ si ara ti ẹmi, 1 Kọrinti 15:45-49; Gẹnẹsisi 3:19; Filippi 3:20, 21.

3 Ọkunrin iṣaaju ti inu erupẹ wá, ẹni erupẹ; Ọkunrin ekeji Oluwa lati Ọrun wá ni 1 Kọrinti 15:39-44; Gẹnẹsisi 3:19; Filippi 3: 20, 21.

**VII Iyipada ti a gbọdọ ni ki A to le Jogun Ijọba Ọrun**

1 Ara oun ẹjẹ kò le jogun Ijọba Ọrun, nitori naa a gbọdọ pa gbogbo wa lara dà 1 Kọrinti 15:50-54; Johannu 8:36.

2 Isa okú ti sọ iṣẹgun rẹ nù, ikú si ti sọ oró rẹ ti i ṣe ẹ̀ṣẹ nù, 1 Kọrinti 15: 55, 56.

3 Iṣẹgun nipa Jesu Kristi a maa rú ifẹ isin tootọ soke ninu ayé, 1 Kọrinti 15:57, 58.

## ALAYE

Odindi ori iwe kan ni Paulu Apọsteli fi ṣe alaye lori ajinde ara, Lootọ, Ajinde jẹ́ ọkan ninu awọn koko pataki ti o n hàn ninu pupọ awọn episteli ti o kọ. Ninu awọn irin-ajo rẹ fun itankalẹ Ihinrere o n waasu ajinde fun awọn Ju ati Keferi lai si ibẹru.

Ki ni ṣe ti Paulu fi tẹnu mọ́ ọran ajinde? Nitori pe ṣaaju ohun gbogbo, "Bi a kò ba ji Kristi dide, asan ni igbagbọ́ nyin ẹnyin wà ninu ẹ̀ṣẹ nyin sibẹ" (1 Kọrinti 15:17). Nitori naa, ireti igbala kò si, kò si ireti Iye ainipẹkun, kò si ireti Ọrun, afi bi otitọ pe Kristi ti inu iboji jade, nipa eyi ti O si já ide ikú ati ti ọrun apaadi ba fẹsẹ mulẹ ṣinṣin lai si tabitabi ninu ọkàn. Nitori lori otitọ ajinde Kristi ati ti ikú Rẹ̀ ni gbogbo ẹkọ Ihinrere ati gbogbo Igbagbọ́ awọn Onigbagbọ́ rọ̀ mọ́. "Bi o ba ṣe pe ni kiki aiye yi nikan ni awa ni ireti ninu Kristi, awa jasi aboṣi julọ ninu gbogbo enia" (1 Kọrinti 15:19).

**Otitọ ti Ajinde Kristi**

Nitori idi eyi ni Paulu Aposteli fi tẹ̀ siwaju lati fi ẹsẹ Ajinde mulẹ; Ekinni, nitori pe Iwe Mimọ́ wi bẹẹ. Ọdun mẹtadinlọgọta lẹhin ti a bi Jesu Kristi (47 AD) ni Paulu kọ Episteli rẹ kin-in-ni si awọn ara Kọrinti. Ni akoko yii, Ihinrere ti Matteu ati ti Luku wà ni arọwọto rẹ, awọn iwe meji wọnyii ni o sọ pupọ nipa ajinde Jesu. O si ni anfanni pẹlu lati ri Iwe Majẹmu Laelae eyi pẹlu ti o kún fun ọ̀pọlọpọ asọtẹlẹ nipa Jesu, ikú ati ajinde Rẹ̀.

Ekeji, ọ̀rọ Paulu duro lori ẹri ti o daju lati ẹnu awọn Apọsteli mọkanla ati awọn ara ti o ju ẹẹdẹgbẹta lọ, gbogbo awọn ti o bá Jesu rìn ti wọn si ba A sọrọ laaarin ogoji ọjọ lẹyin ajinde Rẹ̀. Pupọ ninu awọn ẹlẹri wọnyii ni o wa laaye nigba ayé Paulu, bi o tilẹ jẹ pe diẹ ninu wọn ti sùn. Nipa awọn ẹlẹri wọnyii ni Peteru sọ ninu iwaasu rẹ fun Kọrneliu ati awọn ara ile rẹ: "Awa si li ẹlẹri gbogbo ohun ti o (Jesu) ṣe, ni ilẹ awọn Ju, ati ni Jerusalẹmu; ẹniti wọn pa, ti wọn si fi gbekọ sori igi: On li Ọlọrun jinde ni ijọ kẹta, o si fi i hàn gbangba; ki iṣe fun gbogbo enia, bikoṣe fun awọn ẹlẹri ti a ti ọwọ Ọlọrun yàn tẹlẹ, fun awa, ti a baa jẹ, ti a si ba mu lẹhin igbati o jinde kuro ninu okú:" (Iṣe Awọn Apọsteli 10:39-41).

Ati nikẹyin gbogbo wọn, Jesu tikara Rẹ̀, ani Kristi ti O jinde mú Paulu tikara rẹ, bi ẹni ti a bi ṣiwaju akoko rẹ ni ọna Damasku nibi ti o gbe ti n lọ mu awọn ọmọ-lẹyin Ọkunrin ara Nasarẹti nì. Eyi kọja iran: o ri I, o si ba A sọrọ lojukoju ninu itanṣan ogo. Ati nipa bayii pẹlu, Paulu pẹlu di ẹlẹri ojukoju ti ajinde Oluwa, o ni ẹtọ kikun lẹyin iyipada iyanu rẹ lati jẹ́ ọ̀kan ninu Apọsteli mejila.

**Awọn Miran Sẹ Ajinde Kristi**

Bi o tilẹ jẹ pe ẹgbẹ nla awọn ẹlẹri rere, ẹ̀ri awọn ti a kò le ṣiyemeji rẹ ati eyi ti ile-ẹjọ ode-oni le gba lẹsẹkẹsẹ bi ẹri ododo, ti fi ẹsẹ ajinde Jesu Kristi mulẹ ṣinṣin, sibẹ awọn kan wà nigba ayé Paulu Apọsteli

ti wọn gbọ́ ẹri Ajinde ṣugbọn ti wọn sẹ ẹ patapata. Awọn ara Ateni ni oke Areopagu feti si Iwaasu Paulu, ṣugbọn nigba ti o bẹrẹ si i sọrọ nipa ajinde, awọn kan ninu wọn bẹrẹ si i ṣẹfẹ.

Ṣugbọn aigbagbọ kò pin si igba ayé Paulu nikan. Awọn ẹlẹsin igbalode ti ode-oni kò sẹ́ ajinde nikan, ṣugbọn wọn kọ gbogbo ohun wọnni ti o ju agbara ẹda ati awọn iṣẹ iyanu ti o wà ninu Bibeli. Ninu iru isin bayii, gbogbo ipilẹ ti Igbagbọ́ Onigbagbọ́ duro le lori ni o ti wó lulẹ. Ẹlẹsin igbalode tikara rẹ̀ paapaa mọ eyi ṣugbọn lati kin ipo rẹ̀ lẹyin, o pe awọn ipilẹṣẹ ẹkọ nla ti inu Bibeli ti i ṣe ipo Ijọ iṣaaju ni ohun asán ati itan atọwọdọwọ ti igba ayé atijọ. Ogunlọgọ ile-isin ti o ti ni igbagbọ lẹẹkan ri ti wọn si ti duro lori awọn ẹkọ Kristi ati ti awọn Apọsteli Rẹ̀, ni ẹkọkẹkọ ti isin igbalode yii ti gbilẹ ninu wọn. Lilọ kuro ninu igbagbọ́ ti igba ikẹyin ti n ṣẹlẹ.

**Idaniloju Ajinde Awọn Onigbagbọ́**

Ipilẹ igbala Onigbagbọ́ bẹrẹ ni akoko ti oun gẹgẹ bi ẹlẹṣẹ ba mọ iwuwo ẹ̀ṣẹ rẹ̀ ti o si fi ibinujẹ ẹni iwa-bi-Ọlọrun ronupiwada ẹ̀ṣẹ rẹ̀, ti o si ri idalare gbà nipa igbagbọ́. Ṣugbọn igbala rẹ̀ kò pin si iriri yii nikan tabi ninu awọn iriri kikun ti isọdimimọ ati ti ifi agbara Ẹmi Mimọ wọ-ni. Ninu gbogbo irin rẹ̀ gẹgẹ bi Onigbagbọ́ ni igbala rẹ̀ n tẹ̀ siwaju si i titi oun yoo fi di pipe ti a o si ṣe e yẹ fun Ijọba Ọrun. Gẹgẹ bi Peteru Apọsteli ti wi bayii pe: "Ẹniti ẹnyin fẹ lairi, ẹniti ẹnyin gbagbọ, bi o tilẹ ṣepe ẹ kò ri I nisisiyi, ẹnyin si nyọ ayọ̀ ti a kò le fi ẹnu sọ, ti o si kun fun ogo: **Ẹnyin si ngbà opin igbagbọ́ nyin, ani igbala ọkàn nyin"** (1 Peteru 1:8, 9).

A si ti ka a pe a fi ikú ati **ajinde** Oluwa wa Jesu Kristi ṣe edidi "iru igbala nla bi eyi." Ṣugbọn ajinde Kristi ninu ara fun wa ni idaniloju ti o tayọ igbala ayeraye. Iṣe-iyanu ti o ga ninu awọn iṣẹ iyanu nì pẹlu mu ki ajinde ara ẹni to ba jẹ olooотọ si Olupilẹṣẹ igbala wa ayeraye ki o daju. "Njẹ nisisiyi Kristi ti jinde kuro ninu okú, **o si di akọbi ninu awọn ti o sùn**. . . . . Ṣugbọn olukuluku enia ni ipa tirẹ̀: Kristi akọbi; **lẹhin eyini awọn ti iṣe ti Kristi ni bibọ rẹ̀"** (1 Kọrinti 15:20, 23). Ileri ajinde ara yii jẹ́ ireti Ijọ Ọlọrun lati ọdun-mọdun wá. Ijọ ti o ba ti sọ ireti yii nù ti kú. Gbogbo awọn Onigbagbọ tootọ n fi oju sọna si Ọjọ Idande nla nì: "Nitori Oluwa tikararẹ̀ yio sọkalẹ lati ọrun wá ti on ti ariwo, pẹlu ohun olori awọn angẹli, ati pẹlu ipè Ọlọrun; **awọn okú ninu Kristi ni yio si kọ́ jinde:** Nigbana li a ó si gbà awa ti o wà lãye ti o si kù lẹhin soke pẹlu wọn sinu awọsanma, lati pade Oluwa li oju ọrun: bẽli awa o si má wà titi lai lọdọ Oluwa" (1 Tessalonika 4:16, 17). "A kò si ti ifihàn bi awa o ti ri; awa mọ pe, nigbati a bá fi han, a o dabi rẹ̀; nitori awa o ri i ani bi on ti ri. **Olukuluku ẹniti o si ni ireti yi ninu rẹ̀ a wẹ̀ ara rẹ̀ mọ́ ani bi on ti mọ́"** (1 Johannu 3:2, 3).

**Irapada Ara**

Ara iyara Onigbagbọ yoo ni iyipada ijinlẹ ni Ọjọ Irapada, ani lẹyin igba ti O ba ti pada di erupẹ nibi ti o gbe ti wá, ti o si ti dibajẹ ati ti o ti wà ni ọpọ ọdun ninu iboji. "Gẹgẹ bi Baba ti ni iye ninu ara rẹ̀; gẹgẹ bẽli o si fi fun Ọmọ lati ni iye ninu ara rẹ̀. . . . . wakati mbọ̀ ninu eyiti gbogbo awọn ti o wà ni isà okú yio gbọ́ ohun rẹ̀, nwọn o si jade wá" (Johannu 5:26, 28, 29). "Bi Ẹmi ẹni ti o ji Jesu dide kuro ninu okú ba ngbe inu nyin, ẹniti o ji Kristi Jesu dide kuro ninu okú yio fi Ẹmi rẹ̀ ti ngbe inu nyin sọ ara kikú nyin di ãye pẹlu" (Romu 8:11). Paulu fi iyipada ijinlẹ ti ara wé irugbin ti a gbin: "Ohun ti iwọ fọnrugbin ki iyè bikoṣepe o ba kú: Ati eyiti iwọ fọnrugbin, ara ti mbọ̀ ki iwọ fọnrugbin, ṣugbọn irugbin lasan ni, ibá ṣe alika, tabi irú miran. Ṣugbọn Ọlọrun fun li ara bi o ti wù u, ati fun olukuluku irú ara tirẹ̀" (1 Kọrinti 15:36-38). Eyikeyi ti iyipada iyanu yii le jẹ́ nigba ti ipe ba dún, a fi wa lọkàn balẹ pe a o pa ara kiku dà si eyi ti yoo le ba ara ogo rẹ̀ mu: "Nitori ilu-ibilẹ wa mbẹ li ọrun: lati ibiti awa pẹlu gbé nfojusọna fun Olugbala, Jesu Kristi Oluwa: Ẹniti yio sọ ara irẹlẹ wa di ọtun ki o le bá ara ogo rẹ̀ mu, gẹgẹ bi iṣẹ-agbara nipasẹ eyiti on le fi tẹri ohun gbogbo ba fun ara rẹ̀" (Filippi 3:20, 21). Ki yoo si si irora, ibanujẹ ati ikú ti a n ṣe alabapin rẹ̀ nigba ti a gbé ara aikú yii wọ̀. "Ọlọrun yio si nù omije gbogbo nù kuro li oju wọn; ki yio si si ikú mọ́, tabi ọfọ, tabi ẹkún, bẽni ki yio si irora mọ́: nitoripe ohun atijọ ti kọja lọ" (Ifihan 21:4).

*"Arinrin-ajo ati alejo ni mi;*
*N ko si le duro ju oru ọjọ kan;*
*Ma ṣe da mi duro nitori emi*
*N lọ sibi orisun ayeraye."*

*Ni ilu nì ti emi nlọ,*
*Oludande mi ni imọlẹ ibẹ̀;*
*Kò si ọfọ tabi ibanujẹ,*
*Kò si omije tabi ikú nibẹ."*

**AWỌN IBEERE**

1. Ki ni ṣe ti Paulu fi fi odindi ori iwe ti o gun ju ninu Episteli fun ẹkọ ajinde?
2. Awọn ẹkọ Ihinrere pataki wo ni o rọ̀ mọ́ ajinde ara Jesu Kristi?
3. Awọn ẹlẹri ojukoju wo ni Paulu kó jọ lati fi idi ọran Ajinde Jesu mulẹ?
4. Awọn ẹlẹsin ode oni wo ni o sẹ ajinde? Ipalara wo ni eyi mu ba Ijẹwọ Onigbagbọ́?
5. Idaniloju wo ni ajinde Jesu fún awọn Onigbagbọ́?
6. Ki ni Paulu fi iyipada ti yoo ṣẹlẹ si ara nigba ajinde wé?
7. Ki ni diẹ ninu awọn ibukun ti ara ologo yoo ni?